# Ìṣẹ́ tí à ń fi Àwàdà Jẹ́ nínú Fíìmù Àgbéléwò Yorùbá

*Mordi, Ajọkẹ́ Ọmọ́wùnmí, PhD*

Àṣamọ̀

*A rí i wí pé kò sáábà sí fíìmù àgbéléwò Yorùbá kan tí ìpín àwàdà kì í sí nínú rẹ̀, kódà, àwọn fíìmù Yorùbá kan wà tí ó jẹ́ pé kìkì àwàdà ni láti ìbẹ̀rẹ̀ títí dé ìparí eré. Àwọn òǹwòran kan kóríìra ìpín àwàdà nínú fíìmù, àwọn míràn sì rí ìpín náà gẹ́gẹ́ bí ìpín ìfàkókò ṣòfò. Ohun tí pépà yìí yóò síṣọ lójú eégún rẹ̀ ni pé, àwàdà ṣíṣe nínú fíìmù kì í ṣe fún pípanilẹ́ẹ̀rìn ín lásán, ó ní iṣẹ́ pàtàkí tí ó ń ṣe láàrin gùngùn ibi tí wọ́n ti lò ó àti iṣẹ́ pàtàkì tí wọ́n fẹ́ fi jẹ́ fún àwùjọ. Pépà yìí yóò fún àwàdà ní oríkì, yóò tọpinpin orírun àwàdà, yóò sì tọ́ká sí àwọn aláwàdà láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, bákan náà ni yóò sì ṣe ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ tí a fi àwàdà jẹ́ nínú fíìmù àgbéléwò Ìrù Ẹṣin, Ẹbí Ọlọ́kadà àti Lẹ̀pa Shandy. Oríṣiríṣi ọ̀nà ni àwàdà má a ń gbà wáyé nínú fíìmù àgbéléwò Yorùbá. Ó má a ń wáyé láàrin ọ̀gá sí ọmọ ìṣẹ́, ó wọ́pọ̀ láàrin àṣẹ́nuọ̀nà ìloro sí àwọn àlejò tí ó ń wá ọ̀gá rẹ̀ wá, ó sì lè jẹ́ ìrísí, ìwọṣọ tàbí ọ̀nà tí ẹnìkàn ń gbà sọ̀rọ̀ ní yóò ma pa òǹwòran lẹ́rìn ín. Òògùn ìwòsàn ńlá ni ẹ̀rín rírín jẹ́ fún àgọ́ ara ènìyàn, èyí sì jẹ́ ìdí pàtàkì jùlọ tí àwọn onífíìmù ṣe má a ń ṣe àmúlò rẹ̀. Fíìmù míràn wà tí ó má a ń gba omijé lójú àwọn òǹwòran ṣùgbọ́n kàkà kí òńwòran bẹ̀rẹ̀ sí ní sunkún, ìpìn tí yóò tẹ̀lé ìṣẹ̀lẹ̀ alekoko bẹ́ẹ̀ yóò jẹ́ ìpín àwàdà láti lè má fún òǹwòran láàyè láti banújẹ́. Nígbà míràn ẹ̀wẹ́, àwàdà nínú fíìmù má a ń jẹ́ ìdọ́gbọ́n sojú abẹ níkò ó nípa ohun tí ó ń lọ ní àwùjọ.*

*Kókó ọ̀rọ̀:* *àwàdà, aláwàdà, fíìmù àgbéléwò, àwàdà nínú fíìmù Yorùbá, ìtúpalẹ̀ fíìmù*

## Ìfáárà

Gẹ́gẹ́ bí a ti rí i ka nínú iṣẹ́ Fájìnmí (1993) àwọn onímọ̀ bí i Rótìmí (1968), Adédèjì (1978), Adétúnjí (1987) àti Ògùndèjì (1988) ti ṣe ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ lórí ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè eré oníṣe. Fún ìdí èyí, a ó ṣe àgbéyẹ̀wò ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè àwàdà gẹ́gẹ́ bí i apa kan nínú eré oníṣe, a ó ṣe àyẹ̀wò bí àwàdà ṣe bẹ̀rẹ̀, oríkì àwàdà àti iṣẹ́ tí à ń fi àwàdà jẹ́ nínú fíìmù àgbéléwò Yorùbá.

Níwọ̀n ìgbà tí a ti ṣàwárí wí pé àwàdà ṣíṣe kì í ṣe fún ìpanilẹ́rìn ìn lásan, a ó ṣe ìtúpalẹ̀ ọ̀gangan àwàdà àti iṣẹ́ tí wọ́n fi àwàdà bẹ́ẹ̀ jẹ́ nínú fíìmù àgbéléwòYorùbá mẹ́ta tí àkọlé rẹ̀ ń jẹ́ Ìrù ẹṣin láti ọwọ́ Ẹbùn Olóyèdé, Ẹbí Ọlọ́kadà láti ọwọ́ Gbenga Adéwùsì àti Lẹ̀pa Shandy láti ọwọ́ Yọmí Ògúnmọ́lá.

## Kínni Àwàdà?

A kò lè sọ̀rọ̀ àwàdà kí á má sọ̀rọ̀ kọ́mẹ́dì nítorí nǹkan kan náà ni wọ́n jẹ́. Nínú ìwé atúnmọ̀ èdè kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ The universal Dictionary of English Language (1970) ó rí Kọ́mẹ́dì bí i:

> *The branch of drama which deals in humorous familiar events, passion and motives which exhibits characters speaking the language of everyday life.*

(Ẹ̀ka eré oníṣe tí ó dá lórí ìpanilẹ́rìn ín láti ara ìṣẹ̀lẹ̀, ìmọ̀sílára àti èrò nǹkan tí a mọ̀ láwùjọ, a sì má a ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ẹ̀dá ìtàn tí ó má ń lo èdè ojoojúmọ́ láti fi gbé èrò wọn jáde.)

Bergson (1981) defines comedy as:

> *. . . an imitation of life, a glass of custom, an image of truth. Comedy holds the mirror up to nature and reflects things as they are to the end that society may recognise the extent of its shortcoming and the folly of its ways and set about its improvements.*
>
> (Ìsínnijẹ ìṣẹ̀lẹ̀ ojú ayé, àwòrán, àṣà àti àwọn eré tí ó jẹ́ òdodo. Kọ́mẹ́dì ni jíńgí èyí tí ó ṣe àfihàn ohun tí ó ṣẹlẹ̀ láwùjọ àti láti jẹ́ kí àwùjọ rí àìṣedéédé àti ìwà òmùgọ̀ rẹ̀ kí wọ́n sì gbé ìgbésẹ̀ láti tún un ṣe.)

Gẹ́gẹ́ bí oríkì tí Bergson kì yìí, a r í i wí pé àwàdà jẹ́ ọ̀kan nínú ohun tí a fi ń dẹ́kun ìwà ìbàjẹ́ láwùjọ.Nínú ìwé yaágbó-yaájù tí a mọ̀ sí Mgraw-Hill Encyclopedia of Drama, Volume 1 A-D, p.397, a fún kọ́mẹ́dì ní oríkì báyìí pé:

> *One of the two basic forms of drama differing from tragedy in that it is generally light in tone and has a happy ending. It deals with themes for everyday life rather than with the heroic, with the real rather than the ideal.*
>
> (Kọ́mẹ́dì jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀yà eré oníṣe ṣùgbọ́n tí ó yàtọ̀ sí eré ládojúdé nítorí pé, ìṣẹ̀lẹ̀ rẹ̀ a má a tu ni lára, ìparí rẹ̀ a sì má a mú ayọ̀ lọ́wọ́. Ò dá lórí ìṣẹ̀lẹ̀ ojú ayé ojoojúmọ́ yàtọ̀ sí ìtán a dá lórí akọni).

Bamidele (2001:2) rí àwàdà bí i:

> *Comedy is seen as an imitation just as other forms of poetry but imitation of a base action in that genus of vice which causes laughter.*
>
> (Ìsínjẹ àwọn ẹ̀yà ewì ṣùgbọ́n tí ìsínjẹ yìí dá lórí ìṣẹ̀lẹ̀ kan pàtó tí ó ń ṣẹlẹ̀ láwùjọ, tí àgbékalẹ̀ àfihàn irú ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀ yóò mú ẹ̀rín lọ́wọ́.)

## Àwọn Aláwàdà ní ìran Yorùbá láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀

Kò ṣe é ṣe láti yọ àwàdà kúrò nínú eré oníṣe nítorí pé láti inú eré oníṣe ni à ń gbà yọ ipa àwàdaà jáde. Nítorí náà, a ò lè mẹ́nu ba àwọn tí ó pilẹ̀ àwàdà láì mẹ́nu ba ìlapa àti ìgbéǹde eré oníṣe pẹ̀lú.

Ogunba nínú iṣẹ́ Fájìnmí (1993:11) sọ pé:

> Ní ilẹ̀ Áfíríkà, láti ara ọdún ìbílẹ̀ wọn ni eré oníṣe ti bẹ̀rẹ̀. Nìwọ̀n ìgbà tí ẹ̀yà tí ń bẹ́ ní gbogbo àgbáyé bá sì ní àṣà àti ìṣe ti wọn, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni eré oníṣe ilẹ̀ Áfíríkà jẹ jáde láti ara ìjọsìn fún àwọn òrìṣà bàbáńlá wọn. Bí àpẹẹrẹ, ọdúnÈdí ní ilé Ifẹ̀, ọdún Ògún ní ìlú Òǹdó, ọdún Oluà ní Òsì Èkìtì, ọdún Egúngún ní Ìjẹ̀bú Ìgbó àti ní gbogbo ilẹ̀ Yorùbá, ọdún Ọ̀ṣun ní Òwu Ìjẹ̀bú àti àwọn ilẹ̀ Yorùbá míràn. Gbogbo àwọn ọdún tí a dárúkọ yìí ni ó ní ìlànà eré oníṣe nínú

Fájìnmí sọ ọ́ di mímọ̀ wí pé orin, ìlù, ijó jíjo àti ìlo gàrétà má a ń wà nínú àwọn ohun èèlò ọdún, èyí sì má a ń mú ìlànà eré oníṣe lọ́wọ́, ibi tí wọn bà sì ti ń ṣe eré yìí ní àwàdà ti má a ń jẹyọ. Láti ara ọdún egúngún ni a ti rí àwọn egúngún

alárìnjo tàbí eégún aláre, èyí tí wọ́n má a ń gbé eré wọn láti ìlú kan lọ sí ìlú míràn láti dá àwọǹ ènìyàn lárayá, nínú àríyá wọ̀nyìí náà ni àwàdà tún ti máá ń jẹ jáde láti sọ̀rọ̀ tí ó korò létí ọmọ aráyé.

Nínú iṣẹ́ Fájìnmí náà lati kà á pé Aláàfin Ògbólú tí ó jọba fún ọdúnmẹ́rìn-lélógún ni ó kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ Egúngún Aláre. Ó má a ń fi eré yì í ara rẹ̀ àti àwọn àlejò rẹ̀ lára yá, àwọn ìlú a sì má a pè é láti wá ṣe eré fún wọn nígbà tí wọn bá ń ṣe ayẹyẹ tàbí ìpàdé, pàápàá jùlọ nígbà tí wọ́n bá ń ṣe ayẹyẹ Jàkùta ní àkókò ìgbadé Aláàfin titun. Àwọn eégún míràn tí wọ́n tún máa dáni lárayá ni Ẹyẹbà, Lébe, Ayélabọ́lá, Agbégijó, Àjàǹgìlá àti Ajófẹ́èbó. Àwọn egúngún yìí má a ń fi gàrétà bo ojú wọn, gàrétà yìí a sì má a dẹ́rìn ín pa àwọn ènìyàn. Yàtọ̀ sí èyí, àwọn eégún onígàrétà yìí a má a fi ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ṣe yẹ̀yẹ́ lórí ìwà kan tí wọ́n ń hù tí kò dára, níwọ̀n ìgbà tí òǹwòran kò kúkú mọ ẹni tí ń bẹ lábẹ́ aṣọ, yóò rọrùn fún àwọn eégún náà láti fi àwàdà jẹ́ iṣẹ́ oríṣiríṣi.

Àjàyí nínú Fájìnmí náà sọ nípa àwọn aláwàdà kan tí wọ́n ń pè ní "Àṣá" ní ìlú Ìlọrin. Ààfin ọba ìlú Ìlọrin ni àwọn wọ̀nyìí má a ń wà láti dá ọba lárayá. Àwọn Ẹ̀gbádò náà má ń fi Gẹ̀lẹ̀dẹ́ àti ẹ̀fẹ̀ gbé onírúurú àwàdà jáde. Wọ́n lè má a kọrin tí yóò mú ẹ̀fẹ̀, ìkìlọ̀, ìkansáárásí tàbí ọ̀tẹ̀ lọ́wọ́ láti fi jẹ́ kí ẹni tí wọn ń bá wí mọ̀, kí ó sì lè ṣe àtúnṣe.

Yàtọ̀ sí ohun tí àwọn ẹni ìṣáájú ti sọ nípa àwọn aláwàdà ìgbàanì, Àdìsá (2002) sọ pé, Bàbá kan wà tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ "Ẹríntóge" ní ìlú Ọyọ́. Aláwàdà paraku ni, ọ̀nà tí ó sì ń gbà ṣe àwàdà ni kí òun àti àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ má a sọ ara wọn ní oríṣiríṣi orúkọ, èyí tí ó jẹ́ pé bí wọ́n bá pe ẹnìkan nínú wọn ní orúkọ ọ̀hún, ẹ̀rín àrítàkìtì ni àwọn tí ó bá wà lágbègbè ẹni náà yóò bú sí. Àpẹẹrẹ orúkọ bẹ́ẹ̀ ni; kérédolú, eyínafẹ́, kòrówórojú, Táńtálá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. A gbọ́ pé àwọn Ìlàrí ọba pàápàá jẹ́ ọ̀kan lára àwọn tí wọ́n pilẹ̀ àwàdà ṣíṣe. Àwọn Ìlàrí yìí a má a fá orí kan dá apá kan sí, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìráńṣẹ́ ni wọ́n, síbẹ̀, wọ́n á má a dá àṣà oríṣiríṣi láti pa àwọn ènìyàn lẹ́rìn ín.

Nínú Àdìsá (2002), a tún rí i kà pé, Aláwàdà kan náà wà tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Nípẹ̀là. Òun ni ó dà ijó jíjó sílẹ̀. Láyẹ àtijọ́, bí àwọn ènìyàn bá fẹ́ ṣe ṣíṣe, Nípẹ̀là àti àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ ni yóò dá àwọn ènìyàn lárayá. Ibi tí wọ́n bá sì ti ń ṣe eré wọn, wọ́n a má a dọ́gbọ́n fi àwàdà sín àwọn ènìyàn ní gbẹ́rẹ́ ìpàkọ́. A gbọ́ pé Ọpálábà náà jẹ́ ọ̀kan lára àwọn aláwàdà ìwáṣẹ̀. Ọpálábà kì í ṣe eégún, kò ní orírun ṣùg-bọ́n ó ní ọ̀rẹ́ kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Ọrúnmìlà. Ọpálábà a má a dárà oríṣiríṣi níwájú ọba, bí ó ti ń gbókìtì bẹ́ẹ̀ náà ni yóò ma tàkìtì ọ̀bọ pẹ̀lú owó éyọ tí ó fi ṣe ẹ̀ṣọ́ sára jìngbẹ̀nẹ̀. Nígbà tí ó bá ń dára, àwọn ohun ọ̀ṣọ́ ara rẹ̀ yìí jẹ́ èyí tí ó ń panilẹ̀rìn ín, tí gbogbo ènìyàn yóò sì má a hó gèè, inú wọn a má a dùn, wọ́n á sì má a jó.

Bákan náà, eégún kan wà ní Mòro lẹ́bàá Ìpetumodù èyí tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ "Adékòjọgbọ̀n." Arọ ni eégún yìí ṣùgbọ́n ó má a ń fò ni nígbà tí ó bá ń rìn. Bí ó ti má a ń ṣe àwàdà tirẹ̀ ní pé, yóò ní kí gbogbo ènìyàn má a lu òun, bí àwọn èèyàn ìbá à fẹ́ ẹ̀ lu eégun yìí pa, yóò ní wọn kò tí ì na òun, àwọn ènìyàn yóò sì má a rẹ́rìn ín.

Eégún kan tún wà tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ "Díílù." Ìtàn àdáyébáni eégún yìí má a ń sọ Ṣùgbọ́nojú kan náà tí ó bá dúró sí ni yóò ti má a sọ ìtàn látàárọ̀ di alẹ́. Àwọn ìtàn rẹ̀ yìí má a ń dáèèyàn láràyá, a má a tanijí, ó sì jẹ́ èyí tí ó ń panilẹ́rìn ín. Eégún-kan tún wà tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ "Bọ́badékan" ni Ẹdun Àbọ́n gẹ́gẹ́ bí onípetumodù ti sọ. Gbogbo ìwà àìtọ́ tí àwon ènìyàn má a ń hù ni eégún yìí yóò má a sọ nípa rẹ̀ lọ́kọ̀ọ̀kan nígbà tí ó bá jáde, yóò sì má a ya àwọn ènìyàn lẹ́nu bí eégún náà ti mọ ohun tí ó ń lọ láwùjọ. Èyí sì má a ń jẹ́ kí àwọn ara Ẹdun Àbọ́n má a ṣọ́ra nítorí pé ojú Bọ́badékàn ka ibi gbogbo. Àdìsá (2002: 18-27).

Ìdìde àti ìfìdímúlẹ̀ fíìmù àgbéléwò Yorùbá

Olújìnmí (2004:19) ṣàlàyé pé kí orílẹ̀ èdè Nàìjíríà tó gba òmìnira ní ọdún 1960 ni àwọn Òyìnbó aláwọ̀ funfun tí ó ń ṣàkóso ní ilẹ̀ Nàìjíríà tí ń ṣe àfihàn fíìmù láti fi dá àwọn ènìyàn láràyá. Oun tí fíìmù wọn sì máa ń dá lé lórí ni ṣíse àfihàn àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ìgbàanì (Documentary). Àpẹẹrẹ irú fíìmù bẹ́ẹ̀ tí wọ́n ṣe àfihàn rẹ̀ èyí tí wọ́n pe àkọlé rẹ̀ ní Coronation Scene of Edward VII in Westminster nigbọ́ǹgàn Glover ní ọdún 1903. Nígbà tí yóò sì fi di ọdún 1923, àfihàn sinimá tí ń rinlẹ̀ dáadáa ní ìlú Èkó. Àmọ́ sá, lẹ́yìn òmìnira, àwọn aláṣẹ orílẹ̀ èdè Nàìjíríà rí i wí pé àkóbá ńlá ni fíìmù ilẹ̀ òkèèrè yìí ń ṣe fún èdè àti ìwà ọmọlúwàbí aláwọ̀ dúdú láwùjọ, wọ́n ṣe ìpolońgo bí fíìmù yóò ṣe di gbígbé jádé ní nípa ṣíṣe àfihàn ìwà ọmọlúwàbí ènìyàn dúdú láwùjọ. Olújìnmi ṣàlàyé sìwájú sí i wí pé, ní kété tí ìfilọ̀ ṣíṣe fíìmù aláwọ̀kọ́ṣe àwọn aláwọ̀ dúdú jáde ní àwọn ìran Yorùbá ti tẹ́wọ́ gba èrò yìí wọlé . Fíìmù àkọ́kọ́ tí wọ́n sì gbé jáde ní èdè Yorùbá ni Àjàní Ògún láti ọwọ́ Ọlá Balógun ní ọdún 1976. (Olújìnmí, 2004, Alàmú, 2010 àti Ọláyíwọlá, 2011). Lẹ́yìn èyí, Adédèjì (1971), Jeyifo (1971) àti Ògúndèjì (1988) sọ pé bí a bá ń sọ nípa fíìmù tí a gbé jáde, tí àwùjọ rẹ̀ sì dá lé Yorùbá, Olóògbé Hubert Ògúndé ni ẹni àkọ́kọ́ tí ó kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ sí ni lo fíìmù nínú eré orí ìtàgé ní ọdún 1970. Nìgbà tí àfihàn fiímù àwọn ẹgbẹ́ òṣèrè Ògùndé bẹ̀rẹ̀ sí gbilẹ̀ dàadàa, lẹ́yìn èyì ni a tùn tí tí àwọn ẹgbẹ́ òṣèré míràn náà bẹ̀rẹ̀ sí ní dìde. Àpẹẹrẹ ẹgbẹ́ òṣèré bẹ́ẹ̀ ni àwọn ègbẹ́ òṣèré aláwàdá tí Olóògbé Moses Ọláìyá Adéjùmọ̀ (Bàbá Sàlá) jẹ́ ògúnnágbòǹgbò kàn láàárín wọn.

Tíọ́rì Àmúlò: Tíọ́rì Soṣiọ́lọ́jì Lítíréṣọ̀ (Tíọ́rì Ìmọ̀- Ìbára-Ẹni Gbépọ̀)

Tíọ́rì tí ó wà ní ìbámu pẹ̀lú kókó orí ọ̀rọ̀ tí pépà yìí dá lé lórí ni Tíọ́rí ìmọ̀ –ìbára-ẹni-gbépọ́, nítorí pé, ará àwùjọ ni àwọn aláwàdà nínú fíìmù àgbéléwò Yorùbá jẹ́, wọ́n rínú, wọ́n róde, wọ́n sì mọ ohun tí ó ń lọ ní àwùjọ, ìdí nìyí tí wọ́n ṣe má a ń lo àwàdà nínú fíìmù láti ṣe àfihàn ìjẹgàba àwọn adarí orílẹ̀ èdè lórí ará ìlú àti láti lè jẹ́ kí ìjọba mọ ohun tí àwọn ara ìlú ń là kọja. Lọ́nà kejì ẹ̀wẹ̀, àwàdà ṣíṣe ni ṣe pẹ̀lù ẹnìkan sí ẹlòmíràn, bẹ́ẹ̀ sì rè é, aláwàdà àti ẹni tí à ń ṣe àwàdà sí ará àwùjọ kan náà ni wọn, wọ́n sì lè bá ara wọn ṣeré, mú inú ara wọn dùn, tu ara wọn lára, sojú abẹ ọ̀rọ̀ níkòó tàbí fifi ọ̀rọ̀ sábẹ ahọ́n sọ látàrí àwàdà. Ìtumọ̀ soṣiọ́lọ́jì bí Adéyẹmí (2006: 29) ṣe ṣàlàyé rẹ̀ ni pé, gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó jẹ mọ́ ọmọnìyàn àti

ìbáṣepọ̀ láàrin wọn ní tíọ́rì yìí dálé. Tíọ́rì yìí ń fi ìdí ìmọ̀ nípa ẹ̀kọ́ ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàrin lítiréṣọ̀ àti àwùjọ múlẹ̀. Adéyẹmí (2006:31) sọ pé lára àfojúsùn tíọ́rì yìí ni ṣíṣe àgbéyẹ̀wò àṣà, ìṣe, ẹ̀sìn, èrò, ìṣèlú, ìgbàgbọ́ àti gbogbo ọ̀rọ̀ tí ó jẹ mọ́ ìbágbépọ̀ ẹ̀dá ní àwùjọ.

Adéyẹmí ṣàlàyé pé, Karl Mark àti Fredick Engles tí wọ́n jẹ́ agbátẹ̀rù tíọ́rì yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn kókó àkóónú tíọ́rì yìí ni láti kún fún ìjàjàgbara tábi ìkọlura àgbára, ìjẹgàba àti ìlòdì sí ìjọba, ìjàgbara kúrò lọ́wọ́ àwọn arẹ́nijẹ tàbí alágbára, ohun àlùmọ́ọ́nì àwùjọ àti ètò ọrọ̀ ajé gbọ́dọ̀ jẹ́ àjùmọni, àyípadà rere sì gbọ́dọ̀ dé bá ipò tàbí àyé awà ẹ̀dá láyé, àti pé,ìmọ̀ tí ó kira nípa ètò ìbágbé pọ̀ ẹ̀dá láwùjọ ṣe pàtàkì láti mọ̀. Ìrú ìmọ̀ yìí ni àwon àláwàdà má a ń fi àwàdà gbé kalẹ̀. Ọ̀pẹ̀fèyítìmí (2011: 42) sọ pé, ohun tí tíọ́rì yìí wà fun jùlọ ni láti ṣe àyẹ̀wò lítíréṣọ̀ lápapọ̀ gẹ́gẹ́ bí èso àwùjọ àti èrò báyéṣerí. Afèdèṣọ́nà gẹ́gẹ́ bí àwọn aláwàdà yìí ní iṣẹ́ pàtàkì tí wọn ń rán sí àwùjọ. Eagleton (1976) jẹ́ kí ó di mímọ̀ nínú ìwòye tirẹ̀ wí pé lítíréṣọ̀ ní láti fi ojú òótọ́ hàn lórí èrò báyéṣerí àti láti tako gbogbo èrò tàbí àṣà asọnidèrò ẹ̀yìn nínú àwùjọ gẹ́gẹ́ bí àwọn aláwàdà nínú fîìmù ṣe má a ń fi ọgbọ́n gbé èrò inú wọn àti ìfẹ̀hónú ará ìlú kalẹ̀ nípa àwàdà.

## Aláwàdà lóde òní

Nínú ìṣesí àwọn aláwàdà òde òní láti rí i pé, ọ̀kan-ọ̀n-ni kánún ní ìhùwàsí àwọn àláwàdà àtijọ́ àti ti àwọn òde òní. Onírúurú àwọn ènìyàn ní wọn tí yàn àwàdà ṣíṣe gẹ́gẹ́ bí ìṣẹ́ orí rán ni lóde oní. Pépà yìí ṣẹ àtòjọ orúkọ àwọn alàwàdà náà nípa bí wọn ṣe bẹ̀rẹ̀ àwàdà ṣíṣe láti ìgbà tí eré orí ìtagé ti bẹ̀rẹ̀ kí ó tó dí ohun tí à ń gbélé wò lóde òní. Lára wọn ni: Olóògbé Moses Ọlàìyá Adéjùmọ̀ (Bàbá Sàlá), Káyọ̀dé Ọláníyì Tìjání (Adẹ́rùpọkọ̀), Ayọ̀ọlá Ògúnṣínà (Pápìlolò), Tajudeen ( Gódógbó), (Alúwẹ̀ẹ́), Babatúndé Omidínà(Bàbá Sùwé), Adéwálé Tadénikárò Adéoyè (Ẹlẹ́ṣọ̀ọ́), Abdul-Rahamon Adékúnlé (Dẹ̀jọ Túnfúlù), Yọ̀mí Kíng (Ọ̀pẹ̀bẹ́), Ọmọbọ́lájí Johnson (Bàbá Latin). Bákan náà ni a ní àwọn obìnrin tí wọn yan àwàdà ṣíṣe láàyò gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ òòjọ́. Olóògbé Monsurat Omidina (Mọ́ládùn Kẹnkẹlẹ̀wù) àti Olúfúnkẹ́ Abigael Ọládèjì (Ìyá Níwẹ̀). Yàtọ̀ sí àwọn tí a dárúkọ yìí, àwọn òṣeré kan wà tí a ò dárúkọ gẹ́gẹ́ bí aláwàdà ṣùgbọ́n tí ọ̀rọ̀ ẹnu wọn má a ń panilẹ́rìn ín.

## Ìṣẹ́ tí à ń fi Àwàdà jẹ́ nínú Fîìmì Àgbéléwò Yorùbá

A má a ń lo àwàdà gẹ́gẹ́ bí ìtunilára nínú eré ládojúdè tí ó kún fún ìbànújẹ́, èyí tí ó lè mú kí olùwòran fẹ́ má a sunkún nítorí ohun tí ó ṣẹlẹ̀ sí ẹ̀dá ìtàn kan nínú fîìmù. Ìpín àwàdà má a ń wáyé láti tu òǹwòran lára yálà kí wọ́n tó má a sọkún tàbí tí wọ́n bá ti ń sọkún. A ó ṣe ìtúpalẹ̀ fîìmù Ìrù Ẹṣin láti rí iṣẹ́ tí wọ́n àwàdà jẹ́ nínú fîìmù náà.

### Ìtàn inú fîìmù Ìrù Ẹṣin ní ṣókí

Ọ̀kùnrin kan wà tí ọmọ pọ́n lójú pupọ̀, gbàrà tí ó fẹ́ ìyàwó kejì ní ó bá di bàbá àbíyè. Ìkómọjáde ku ọjọ́ mẹ́ta ni ẹ̀mì àìrí darí ọkunrin náà láti lọ kó sí omi bí ó bá

ti ń wa ọkọ̀ lọ lójú pópó. Ariwo ẹkún sọ, ọ̀fọ̀ ńlá ṣẹ̀. Àṣẹ̀yìnwá, àṣẹ̀yìnbọ̀, ọmọ náà dàgbà, ó dèrò ìlú òyìnbó. Ní ọjọ́ kan, ìyá ọmọ náà lá àlá wí pé ayé fẹ́ ṣe ọmọ rẹ̀ nìkà, ó sì tọ Babaláwo lọ. Babaláwọ ní kó rúbọ, Adépèlé ṣe ètùtù ṣùgbọ́n ẹbọ rẹ̀ ò fín, ìfọ́jú ni wọ́n dà lùú ní oríta tí ó gbé ẹbọ lọ. Lọla ọmọ tí wọn torí rẹ̀ gbẹ́bọ kú, ìrònú àjálú yìí ní ó pa ìyá àgbà wọn. Adépèlé jìyà, wọ́n pa á lọ́kọ, wọ́n pa á lọ́mọ, wọ́n tún bu ìfọ́jú lù ú, kò sì tún dúró jẹun ọmọ kan ṣoṣo tí ó kù fún.

Ọ̀gangan Àwàdà

Nígbà tí eré bá le koko báyìí, tí omí lé róró lójú olùwòran ní a ò déédé rí Bàbá Sùwé pẹ̀lú àkàǹpọ̀ aṣọtí ó wọ̀, èyí tí ìrísí rẹ̀ yì í yóò jẹ́ kí òǹwòran rín ẹ̀rín, kí ó tó di pé bàbá sùwé sọ̀rọ̀ rárá. Bí àpẹẹrẹ, nínú fíìmù yìí, Bàbá sùwe wọ́ ṣòkòtò kẹ̀ǹbẹ̀, ẹ̀wù òtútú aláwọ̀ dọ́rùn , ó sì dé fìlà gogoro kan lé e lórí, ó ń kọrin, ó sì ń gbọ ẹṣẹ̀ pẹ́pẹ́ẹ́pẹ́:

Mandela, Mandela/O lọ fara jìyà nítorí òmìnira/Kọrugitesọn for your fiidọm

Lẹ̀yìn orin yìí, ó gbọ́ tí ẹnìkan kan ilẹ̀kùn, ó sì sá sí abẹ́ Bẹ́ẹ̀dì. Nígbà tí àbùrò rẹ̀ rí i, ó béèrè ìdí tí ó fi sá pamọ́, bàbá sùwé rí i pé àbúrò rẹ̀ ni ẹni tí ó ń kan ilẹ̀kùn, bàbá sùwé sọ pé:

| | |
|---|---|
| Bàbá Sùwé: | Ìwọ tí ẹ̀ ni, Mo ṣe bí àwọn tí mo jẹ lówó ni |
| Àbúrò Bàbá Sùwé: | Àwọn mélòó ni ẹ jẹ lówó? |
| Bàbá Sùwé: | Wọ́n pọ̀ ṣùgbọ́n èyí tí mo jẹ ní ìjẹrin ni ó jẹ́ kí ó di ogún |
| Àbúrò Bàbá Sùwé: | Mò ń mú yín lọ sí Èkó |
| Bàbá Sùwé: | A mu not go see – mi ò lọ, ẹ fẹ́ mú mi lọ Èkó, kí ẹ lọ sọmí sómi, Èkó arómisá lẹ̀gbẹlẹ̀gbẹ, n ò lọ, Òtútù yóò má a mú mi lékòó. |

Lẹ̀yìn ìpín àwàdà yìí ni wọ́n tún ṣe ìpín alekoko níbi tí Adépèlé ti gbẹ́bọ, tí ojú rẹ̀ sì fọ́. Ìdààmú tí Adépèlé ń dojú kọ kò ṣe é fẹnusọ, ìrírí yìí sì jẹ́ nǹkan tí ó lè gbomijé lójú òǹwòran. Àwàdà tí wọ́n fi ṣe ìtunilára ni ìgbà tí wọ́n mú Bàbá sùwé dé èkó.

| | |
|---|---|
| Bàbá Sùwé: | ( ó ń fi ọwọ́ tẹ ara, ó sì rí i wí pé òun ti tọ̀ọ́lé) Ó ní: Hún ùn, mo tún ti ṣe kinní yìí lékòó. |
| Àbúrò Bàbá Sùwé: | kí ló dé tí ẹ fi tọ̀ọ́lé? |
| Bàbá Sùwé: | mo láàlá pé mò ń lúwẹ̀ẹ́ nínú odò ni. Lẹ́yìn èyí, a rí Bàbá Sùwé níbi tí ó ti lọ kọ́ṣẹ́, lẹ́yìn ẹ̀kọ́ṣẹ́, ó padà sí ìlú rẹ̀, ó ń ṣiṣẹ́ gẹrungẹrun, Bàbá Latin sì wà láti kọ́ iṣẹ́ lọ́dọ̀ rẹ̀. |
| Bàbá sùwé: | Ọlọ́run má jẹ̀ ẹ́ kí á ṣe orí aburú, Kì í ṣe àdúrà tí |

Bááàbà lè gbà nítorí oríṣiríṣi orí ni wọ́n ń gẹ̀. (ẹnìkan wọlé, ó fẹ́ gẹrun)

Bàbá sùwé: Orí rè é bí i Àsálà yìí

Bàbá Latin: Ṣé orí àsálà tún wà ni?

Bàbá sùwé: Orí fùlùfúlù wà, orí ìbẹ́pẹ wà, kò sì irú orí tí kò sí.

Títí tí wọ́n fi parí fîìmù náà ni wọ́n ń fi ìpín àwàdà bọ̀ọ́ ní ààrín. Ohun tí ìpín àwàdà wúlò fún jùlọ nínú fîìmù Ìrù Ẹṣin ni ìtunilára ní ibi tí ìkọniláyà sókè bá ti wà. Bákan náà ni wọ́n lo àwàdà nínù fîìmì yìí láti rí i wí pé agbo ìdákẹ́rọ́rọ́ dí agbo ẹ̀rín.

Fîìmù Ẹbí Ọlọ́kadà ní ṣókí
Kìkìdá àwọn aláwàdà ni wọ́n kó ara wọn jọ láti fi àwàdà tú àṣírí ìwà ibi tí àwọn alágbàwà Ọ̀kadà má a ń hù.

Bàbá sùwé àti Ẹlẹ́ṣọ̀ọ́ ni Dìónà nínú fîìmù náà. Àwọn alágbàwà Ọ̀kadà Ẹlẹ́ṣọ̀ọ́ ń mú owó díẹ̀díẹ̀ wá ṣùgbọ́n àwọn alágbàwà Bàbá sùwé tí orúkọ wọn ń jẹ́ Kówópé àti Òtòlò kò ni kò ní òtítọ́ rárá, o má a ń ṣe owó kúmọkùmọ, ìwà yìí sì má a ń kó ìpayà bá Bàbá sùwé tí ó jẹ́ ọ̀gá wọn. Bí Bàbá sùwé bá jẹun kì í wọnú, bí Kówópé bá ti gbé Ọ̀kadà lọ láti àárọ̀, ó di ìgbá tí ó bá gbé e padà dé kí ọkàn Bàbá sùwé tó balẹ̀. Nítorí ìwà àìlóòótọ́ ní ó mú kí Bàbá sùwé pinnu láti gba Ọ̀kadà rẹ̀ lọ́wọ́ Kówópé àti àwọn alágbàwà tókù, ó sì pín ín fún àwọn mọ̀lẹ́bí rẹ̀.

Ọgangan Àwàdà àti iṣẹ́ tí wọ́n fi jẹ́

Kówópé: Fáìfù édéédì nairà (#500) tí mo pa rè é o

Bàbá Sùwé: Mo jẹ́rì í, kówópé, orúkọ ń rò ọ́, ó yá mú kọ́kọ́rọ́ wá

Kówópé: Èyun ùn náà ni mo ní kí n sọ fún yín. Mo gbé ẹnìkan báyìí, ó wá ní kí n kọrí sí ọ̀nà kọ̀rọ̀, ìgbà tí a wá dé ibẹ̀ ó yọ̀bọn sí mi.

Bàbá Sùwé: O ò ya gbọ́kadà rù, kó o má a sá bọ̀ wálé

Kówópé: (Ó ń ṣẹ́jú páúpáú)Bí wọ́n ṣe gbé Ọ̀kadà lọ nìyẹn.

Bàbá Sùwé: wọ́n ṣe kínni? (Bàbá sùwé bẹ̀rẹ̀ sí ní lu kówópé)

Gbogbo ìṣesí Bàbá sùwé nígbà tí ó ń lu Kówópé yìí ni ó ń panilẹ́rìn ín. Bákan náà ní a tún rí alágbàwà Bàbá sùwé míràn tí ó gbé àlè lọ sí ilé oúnjẹ́.

Òtòlò: Béèrè irú oúnjẹ tí ó bá fẹ́

Àlè: Ṣé Iyán wà?

Olóúnjẹ: ó wà

Àlè: Tọ́kì ń kọ́?

Olóúnjẹ: ó wà

Àlè: Ṣé ẹ ní ẹja dúdú?
Olóúnjẹ: ó wà
Àlè: ẹ fún mi ní ìyán mẹ́rin, ẹran ìgbẹ́ márùn ún, tọ́kì márùn ún àti ẹja dúdú márún.
Òtòlò: (Kò lè sọ̀rọ̀, ó ń ranjú ní ìṣesí pé ohun tí àlè béèrè ti pọ̀ jù ṣùgbọ́n kò jẹ́ kí àlè mọ̀) ó ní: Kó o jẹun yó dàadáa, kí o ba lè ráyè ṣiṣẹ́ o.
Àlè: Ṣe bí mo ti ní n ò lè ráyè jáde lónìí, mo ní ode tí mo fẹ́ lọ.
Òtòlò: (Nígbà tí àlè fẹ́ fi ọwọ́ mú Tọ́kì sẹ́nu, òtòlò fi ọwọ́ dábùú àwo, èyí sì jẹ́ ohun tí ó panilẹ́rìn ín nítorí ó rí i wí pé kò sí àǹfààni jíjẹ Tọ́kì, ẹran ìgbẹ́ àti ẹja dúdú nígbà tí àlè kò ní lè bá ohun jáde.) Nígbà tí ó dé ilé Dìónà, ó ní ọjà kò tà
Bàbá sùwé: Báwo lọjà lónìí?
Òtòlò: Kò fi bẹ́ẹ̀ sọ́jà rárá

Lẹ́yìn ìpín yìí ni a rí i tí Bàbá sùwé ń ké pé òun ti fẹ́ ní patẹ́ńṣọ̀n nítorí ìrònú kúmọkùmọ tí wọ́n ń Ṣe ọ̀kadà rẹ̀.

Ní ti Ẹlẹ́ṣọ̀ tí ó jẹ́ Dìónà kejì. Àwọn alágbàwà ń lọ sí ìwájú rẹ̀ lọ́kọ̀ọ̀kan láti dìlífà fún.

Alágbàwà: Ẹ gba #300 nairà yìí ná, bí ó bá di alẹ́, mà á mú #200 tí ó kù wá. Ìyá mi ló dé láti oko wa, wọ́n sì nílò owó, ìdí nìyẹn tí owó yín kò fi pé
Ẹlẹ́ṣọ̀ọ́: Ọ̀kadà tèmi ni ó fi ń bọ́ fámílì, ori rẹ burú ni? Bílẹ̀ bá ṣú tí o kò kó owó mi fún mi, o kẹ́ran.

Ohun tí a lè sọ nípa àwọn ọlọ́kadà méjèèjì ni pé, bí kì í bá Ṣe pé ẸléṢọ̀ọ́ kò gba ojú bọ̀rọ̀ fún àwọn alágbàwà rẹ̀, wọ́n ò bá ti sọ òun náà di ẹdun arinlẹ̀. Fífi àwàdà sọ irú ìwà tí àwọn alágbàwà má a ń hù yìí máa ń jẹ́ kí ẹnikẹ́ni tí ó bá fẹ́ ṣe àgbàwà yála ti mọ́tò ni o tàbí ọ̀kadà jẹ́ olótìítọ́ sí àwọn ọ̀gá wọn. "Kò sí awo kan ní awo ẹ̀wà" níwọ̀n ìgbà ti àwọn òǹworan ti mọ́ irú àṣírí bàyii, yóò ṣòro fún alágbàwà láti kàn déédé má a parọ́ fún ọ̀gá rẹ̀ lórí ohun ti kò ṣẹlẹ̀ nítorí owó.

Fîìmù Lẹ̀pa Shandy

Obìnrin kan ni ó gbé ère òrìṣà kan ti ó má a ń pa kádàrá àwọn ọkunrin tí ó bá a láṣepọ̀ dà. Ọmọ obìnrin kan ṣoṣo tí obìrin náà bí já ìfun ìyá rẹ̀ jẹ, kódà, ìwà ìbàjẹ́ ọwọ́ tirẹ̀ tún ju ti àgbèrè lọ. Ọmọ yìí tún lu jìbìtì, ò sì tún ń gbé òògùn olóró lọ sí òkè òkun. Bàbá sùwé kó sákóló òbinrin yìí ṣùgbọ́n orí yọ ọ́ nígbẹ̀yìn. Lẹ̀yìn ò

rẹyìn, ọwọ́ pálábá Lẹ̀pa Shandy ségi, àwọn tí wọ́n jọ ń ṣe jìbìtì, gbé òògùn olóró náà ni wọ́n ṣekú pa á. Àṣẹ̀yìn wá, àṣẹ̀yìn bọ̀, obinrin elére nílé yìí náà ya wèrè.

Ọ̀gangan àwàdà àti iṣẹ́ tí wọ́n fi jẹ́
Aláwàdà ni wọ́n fi ṣe olú ẹ̀dá ìtàn nínú fíìmù yìí (onítọ̀ún wá dúpẹ́ lọ́wọ́ ọ̀gá ọmọ rẹ̀)

| | |
|---|---|
| Bàbá sùwé: | Ẹ ǹ lẹ́ mà, mo ní kí n wá dúpẹ́ ni mà. Ṣé tí kì í bá ṣe ti àwọn òṣìṣẹ́ rélùwéè tí kò rí owó oṣù gbà, n ò bá ti fọmọ lọ́sìn ṣùgbọ́n mo dúpẹ́ pé ẹ̀ ń bá mi tọ́jú rẹ̀ |
| Ọ̀gá Táwà: | Kò tọ́ pé, ẹ ò tí ì rí nǹkankan. (obìnrin yìí dide fù ú, ó ní òun ń bọ̀, kí ó tó jáde síta, ó tí fi àṣẹ sẹ́nu) ó sì wí fún Bàbá sùwé pé òun yóò bá a dọ́rẹ̀ẹ́. |
| Bàbá sùwé: | Kí ló dùn bí i Ẹ̀dọ̀ki àti Fùkù. Ṣé ẹ ráyé ìyá Táwà tí kò mọ iyì mi, èèyàn ló ní òun yóò bá mi dọ́rẹ̀ẹ́ yìí (Bàbá sùwé padà délé, ó sì kó jáde fún ìyá Táwà) Òògùn ti bò ó lójú, ọ̀rẹ́ rẹ̀ kan wá wò ó ní ilé tun-tun náà. |
| Alúwẹ̀ẹ́: | Ọjọ́ tá á bá ríbi ni ibi ń wọlẹ̀, ẹnìkan kò lè wá ti orí rẹ̀ babẹ́ níbi |
| Bàbá sùwé: | (Ó tu òwe tí Alúwẹ̀ẹ́ pa, àwọn èèyàn sì bú sẹ́rìn ín) |
| Ọ̀gá Táwà: | Alágbàlá, ṣé ẹ ti fọ aṣọ tí mo ní kí ẹ fọ̀? |
| Bàbá sùwé: | Bẹ́ẹ̀ ni mà |
| Ọ̀gá Táwà: | Àwọn pátá tí mo rẹ ń kọ́? |
| Bàbá sùwé: | mo ti fọ̀ ọ́ mà. (Bàbá sùwé kúnlẹ̀, ó ń rojọ́ ohun tí ọ̀rẹ́ rẹ̀ bá a sọ. ) |
| (Óní): | Ọ̀rẹ́ mi yìí ní ẹ ti ki orí mi babẹ́ |
| Ọ̀gá Táwà: | (ó gbá Bàbá sùwé lójú) Kínní ìwọ́ wí? |
| Bàbá sùwé: | (ó ń fẹ́ má a sunkún) mo ní kò rí bẹ́ẹ̀ (ó kọjú sí Alúwẹ́ẹ̀ ), ṣe o rí ohun tí ó dá sílẹ̀? jáde, jáde, jáde |

Àwọn ẹbí jáde sí ọ̀rọ̀ Bàbá sùwé, wọ́n ní kí Táwà wọ́n ọmi tí wọ́n ti ṣe aájò sí sí bàbá rẹ̀ lára, wàì ni ojú rẹ̀ dà tí ẹ̀mí buruku náà sì jáde lára rẹ̀. Ní kété tí ọ̀gá Táwà wọlé ní ẹ̀mí burúkú tí ó jáde lára Bàbá sùwé wọlé sí i lára, ó sì bẹ̀rẹ̀ sí ni ṣe wọ́n-ran wọ̀nran.

Iṣẹ́ tí a fi àwàdà jẹ́ nínú fíìmù náà
Ẹ̀kọ́ pàtàkì tí fíìmù yìí fi àwàdà kọ́ àwọn ọkùnrin ni láti má a ṣora gidigidi nítorí àwọn obìnrin tí ó ń ki orí ọkọ wọn tàbí ọkọ ọlọ́kọ bọ abẹ́, kí àwọn ọkùnrin lè

kó sí pańpẹ́ àwọn ìkà obìnrin tí ń pa kádàrà ọkùnrin dà. Fîìmù yìí tún fi àwàdà ṣe ìkìlọ̀ fún gbogbo àwọn tí ń gbé òògùn olóró pé kí wọ́n jáwọ́ níbẹ̀ nítorí pé àtubọ̀tán rẹ̀ kìí dára. Fîìmù yìí tún fi àwàdà ta aráàlú lólobó nípa àwọn òṣìṣẹ̀ ilé iṣẹ́ rélùwéè tí wọn kò rí owó oṣù gbà lọ́wọ́ ìjọba, èyí tí ó jẹ́ wí pé bí kìí bá ṣe pé wọ́n fi àwàdà sọ ojú abẹ níkòó, tí wọ́n sì fi àwàdà gbé ẹ̀hónú àwọn òṣìṣẹ́ ilé iṣẹ́ rélùwéè hàn, ìbá tí sí pé ìjọbá rí sí ọ̀rọ̀ tí ó ní ṣe pẹ̀lú àjọ ilé iṣẹ́ rélùwéè rárá.

Agbálọgbábọ̀

A lè sọ wí pé ìṣẹ́ tí à ń fi àwàdà jẹ́ ni sísọ òtítọ́ tàbí òkodoro ọ̀rọ̀, ìtanilólobó, ìdáni nínú dun, ìfiniṣefe, ìtunilárá, títàbùkùn ìwaasù èkè àti ìwa ìbajẹ̀ láwùjọ. Aláwàdà ní àǹfààní àti sọ gbogbo ohun tí ó ń lọ láwùjọ tàbí pe àkìyèsí ìjọba sí ohun tí ó ń lọ nílùú bí i ọ̀rọ̀ ọ̀wọ́ngógó epo rọ̀bì, àìríṣẹ́ ṣe, àwọn ọ̀bàyéjẹ́, ọ̀rọ̀ lórí àwọn agbófinró, òṣìṣẹ́ nẹ́pà, àjọ olómi àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nígbà míràn tí ìlú bá fẹ́ yí ọ̀rọ̀ mọ́ àwọn aláwàdà lọ́wọ́ lórí ohun kan tí wọ́n sọ, àwọn aláwàdà yóò wí pé àwọn kò bá ẹnikẹ́ni wí nítorí pé àwọn kò dárúkọ ẹnikẹ́ni, àwàdà lásán ni àwọn ń ṣe.

Lákòótán, àwàdà ṣíṣe kì í ṣe fún pípanilẹ́rìn ín lásán, iṣẹ́ pàtàkì ni wọ́n fi ń jẹ́ fún àwùjọ.

## ÌWÉ ÌTỌKASÍ


Adédèjì, J.A. (1971). The Church and the emergence of the Nigerian Theatre 1866-1914. *Journal of the Historical Society of Nigeria*. volume 6(1) pp. 25-45.

Adéyẹmi, L. (2006). Tíọ́rì Lítíréṣọ̀ ní Èdè Yorùbá. Ìjẹ̀bú –Òde: Shebiotimọ Publications.

Adisa, O. A. (2002) .'Aláwàdà nínú fîìmù àgbéléwò Yorùbá" Unpublished B. A project in the Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan, Ibadan.

Àlàmú, O.O. (2010). "" Aesthetic of Yorùbá Film"in journal of Lingua-cultural studies in Ethnic Conflicts of the World. (LICCOSEC). Japan: Record Institute for world Languages Osoka University.

Bamidele, L.O. (2001) . *Comedy*: Ibadan: Stirling –Horden Publishes (Nig) Ltd.

Bergson, Henri (1981). "Form Laughter in comedy': Meaning and form. Robert .W. (ed) New York: Harper and Row publishers, pp. 328-332, second edition

Fajinmi, I.B. (1993). The comdies of Jacob, Papilolo and Aderupoko (The Jester International) M.A, Project, Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan.

Eagleton, T. (1976). *Maxism and Literary Criticism*. California: University of California Press.

Jeyifo, B. (1984). The Yorùbá Popular Travelling Theatre of Nigeria. Lagos: Emascon Print Ltd.

Mcgraw-Hill (1972). *Encyclopedia of Drama*. Volume I (A-D) Printed in the United States of America.

Ògùndèjì. P. A. (1988). "'A Semiotic Analysis of selected Video Film'." Doctoral dissertation, Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan.

Ọláyíwọlá, A. (2011). "" A Semiotic Analysis of Selected Video Film'." Doctoral dissertation, Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan.

Olújìnmí, I.O (2004). "The Portrait of the Female in Video Films'." Doctoral dissertation, Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan,

Ọ̀pẹ̀fèyítìmí, A. (1997). Tíọ́rì àti Ìṣọwọ́lò-èdè. Òṣogbo: Tanímọ̀la Press.